THE EDITOR IMOLE OWURO
23/4/77
IBADAN.

WEEKS 39&40
Kongi WK 39
6 7 14
Wk 40
22 31 43
Asiko BK WK 39
10 12 14 39
Wk 40
27 28 29 48
Ross Wk 39
9 & 17
WK 38
1&20


# Imọlẹ Owurọ

ẸṢIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!


SAMCO OF NIGERIA
WK 39
NAP 18 19 24
Perm 18 19 24 25 27
My Address ?
Not nessesary,
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
**17 24 32**

Independent Paper Vol. XV NO 794 SATURDAY APRIL 23 – FRIDAY APRIL 29, 1977 10K. KOBO MEWA)

25 APR 77

# ABILEKO LU ARUGBO PA NITORI OMI

## --Afesunkanni

AWỌN Ọlọpa Ipinlẹ Kwara ti mu obinrin abilekọ kan, Ẹbun Jacob ti iṣe iyawo ọkunrin Ọlọpa kan, Ọgbẹni Ikuolayọ Moses ti o wa ni ile iṣẹ Ọlọpa ilu Ilọrin.

Obinrin na ni nwọn mu wa sile ẹjọ giga ilu Lọkọja niwaju Adajọ Ọlọla Emmanuel Adeyẹmọ Adewuyi lati koju ẹsun pe, o lu iya arugbo kan, Iyaafin Ibironkẹ Awẹ pẹlu ero lati pa a l'ara.

Iya arugbo na ni awọn afẹsunkanni sọ pe iyawo Ọlọpa na, Ẹbun Jacob, ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu kẹrin ọdun 1975 ba ja ni odo kan lẹba abule Iṣanlu Makuta ni Kansul Oyi ni Ipinlẹ Kwara.

Ohun ti awọn afẹsunkanni sọ pe o da arukutu na silẹ ni omi pipọn.

Nwọn ni ọjọ ti a nwi yi ni iporogan ṣẹlẹ laarin awọn enia mejeeji l'ori taa ni yio kọ pọn omi ninu odo na. Gẹgẹ bi nwọn ti wi, nwọn ni nigbana ni Ẹbun Jacob lu iya arugbo na, Ibironkẹ Awẹ ni igba-aiya.

Gẹgẹ bi nwọn ti wi, nwọn ni lẹsẹkẹsẹ ni Ibironkẹ Awẹ ṣubululẹ ti o si ku bamubamu.

Ọpọ enia l'o jẹri fun Ijọba l'ori ẹjọ na ti nwọn nba Ẹbun Jacob ro. Ara wọn ni ọmọ bibi inu iya arugbo na meji: Ọmọtayọ Awẹ, Ọlọruntọba Awẹ, ẹni ti o jẹri pe Ẹbun l'o lu iya awọn ni ẹsẹ ni igbaaiya.

Bakanna ni ẹlẹri miran, Adelẹyẹ Ọmọkore jẹri nile ẹjọ pe ko pẹ ti iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni oun de odo na ati pe nigba ti oun pe Ẹbun Jacob, nigba ti o fẹ maa lọ sile, nṣe ni o kunlẹ ti o si nbẹ oun pe ki oun ba oun ji iya arugbo na.

### "KO ṢẸLẸ"

Ṣugbọn ninu akọsilẹ rẹ ni ti Ọlọpa ati ẹri ti o jẹ nile ẹjọ, obinrin na, Ẹbun Jacob sọ pe, ọrọ pe oun lu iya arugbo na ko ṣẹlẹ rara.

O ni iya arugbo na l'o tu omi le oun l'ori ni akoko ajaromọsọ ti awọn nṣe na. O ni oun ko gbẹsan l'ara iya na, ohun ti oun kan wi ni pe "Ọlọrun yio ṣe idajọ".

Ṣugbọn ninu ọrọ rẹ fun ile ẹjọ giga na, Agbefọba, Amofin Ọbasa sọ pe, awọn idi mẹrin pataki ti o le mu ki a da Ẹbun Jacob lẹbi ọran na ni awọn afẹsunkanni fi mulẹ.

Agbẹjọro Ijọba na sọ pe, ẹri ti Ọmọtayọ Awẹ, Ọlọruntọba Awẹ ati Adelẹyẹ Ọmọkore jẹ fi idi rẹ mulẹ pe, Ẹbun Jacob l'o fa iku iya arugbo na, Ibironkẹ Awẹ.

Siwaju si i, Agbẹjọro na sọ pe ẹri ti o nbẹ niwaju ile ẹjọ fi han pe, ọrọ pe Ẹbun Jacob ṣeeṣi pa enia ko ṣẹlẹ rara nitori gẹgẹ bi Agbẹjọro na ti wi, "ọdaran na mo,

(Woju Ewe Kẹjọ)


## ADEWỌLE ONILU-ỌLA

GBE TITUN DE

GBAJUMỌ Oniyaalu kan ti ẹ ti nreti ki o gbe Awo titun jade lati ọjọ pipẹ, ti ṣe bẹẹ bayi.

Gbajumọ Olorin na ni Adewọle Animaṣahun ti ẹ mọ gẹgẹ bi "Adewọle Oniluọla" ẹni ti iṣe Aṣaaju Ẹgbẹ Alare apala rẹ.

Nọnba Awo na ni HRCL7 eyi ti yio jade sita fun tita ni 27/4/77.

Adewọle Onilu-ọla ati ẹgbẹ Alare apala rẹ dan nkan wo ninu Awo na. A ko tun ṣẹṣẹ le maa sọ bi ilu inu Awo na ti dara to gẹgẹ bi ẹ ti mọ pe oniyaalu ti yio fi ọwọ ro Adewọle sẹhin sọwọn ni Naijiria.

Orin inu rẹ fakiki, o mu ọgbọn dani, o wu ni lori, o kọ ni lọgbọn, o dun i lo l'awujọ: Nasia atata ni, iwaasu ti o galọla ni, orin faaji ti ko l'egbẹ ni, nbẹ ninu Awo na pẹlu.



Adewọle Onilu-Ọla

Irohin ko to afetigbọ, afetigbọ ko to ki a ni ti ara ẹni, ni ọrọ Awo na jẹ. Tete lọ ra ki o si maa fi igbadun ṣ'ayọ pẹlu Awo Adewọle Onilu-Ọla.

Olupinja Awo na ni:
HASBUNALAU TRADING COMPANY
561, L. E.D. B. SHOP,
BALOGUN STREET,
EKO
ATI NI:-
* 27, Willoughby Street,
L'ẹba Ọja Oyingbo,
Ebute-Mẹta.


## Ina pa omo iya meji

IROHIN lati ilu Ado Ekiti ni Ipinlẹ Ondo fi ye wa pe, ina Lẹntiriki ti pa awọn ọmọ iya meji ku finin-finin ni ilu na.

Ni adugbo Odo–Ado nilu Ado-Ekiti ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ. Orukọ awọn ọmọ iya meji na ni Lasisi Jinadu ati Jimọ Jinadu.

Ẹnikan ti ọrọ na ṣoju rẹ sọ pe, lẹhin ti ojo ti rọ ni ọjọ ti a nwi yi ni eyi Lasisi Jinadu mu aṣọ rẹ ti ojo pa lọ si ẹhinkule ile wọn lati sa a. Nwọn ni bi o ti sa

(Woju Ewe Kẹjọ)


## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Machine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:

## ATIORO ỌMỌ ATIALA

### Oore t'o dara (6)

A ti sọ fun nyin
Iru oore ti ko tọ
T'ọmọ araiye nṣe pata;
T'ẹda ko si mọ
Pe, oore ọhun ko l'abọ.
A ti so fun ọ to ọrẹ,
Nṣe ni ki o dẹhin
Nibi oore
Ti ko ni ẹsan;
Ki o pẹhinda
Ki o ṣoore
T'o dun mọ *O*dumare.
O ko bi mi pe:
Iru oore wo l'o tọ
T'o ye k'a maa ṣe ?
O ko si beere
Iru iwa t'o t'ọna
K'ọmọ Aadamọ o hu?
Gbogbo oore
T'o ba ti jẹ
Eyi ti o ti inu wa,
Gbogbo oore ẹwẹ
Ti a mu
Lati odo ikun;
Oore atọkanwa
Ti a ṣe f'ẹni t'o tọ si
Lai naani ẹsan;




Ti a ko si gbeleju
Ti a ko fi sinregun
S'ọmọ ẹnikeji.
Oore ti ki iṣe
Oore arọju-ṣe,
Ti ki i ṣe ti tulaasi,
Ti ki i ṣe, mẹnukuro,
Ti ki i ṣoore ẹdẹ,
Ti ki i ṣe
Oore "gba jẹ ng sinmi,"
Iru oore wọnyi
L'Oluwa mi nilo.
Taa ni ninu nyin
Ẹnyin ni nba wi ?
T'o ti ṣoore ri
T'o jẹ pe,
Gbogbo ẹni pata
T'o ṣoore fun
L'o s'ẹsan oore ?
Taa l'o ṣe 'ranwọ
F'ọmọ adamọ
T'o le Awọsọya
Pe, gbogbo fọ wọn
L'o san aarọ pada?
Enia melo
L'o le fọwọsọya
Pe, n'ijọ oun ti daiye
Ogede ẹni pata
T'oun ṣe l'oore ri
L'o ṣe f'oun na san ?
Taa ni ko jẹ
Anfani ọpọ enia
Lai jẹ pe
A ti mọ onitọhun tẹlẹ ?
O pakiti mọri
O gba ẹhin odi lọ:
O de ajo tan,
Nwọn ngbe ọ ga,
Nwọn nti ọ lẹhin
Ẹni ti o ko mọ ti,
Ẹni ti o ko riri,
Ẹni ti
Ko ba iran rẹ tan,
Gbogbo wọn ri ọ
Nwọn ṣe ọ loore !
Njẹ: Yala iwọ,
Baba t'o bi ọ,
Tabi enia rẹ kan
Ha ri wọn ri
Ti a ba fi sọ pe,
Bọya ẹsan oore
T'o ti pẹ, t'o ti pẹ,
Ni nwọn nsan fun ọ ?
Tabi o kọ r'ajo ri
Ki o le jẹri ọrọ ?
Idi na niyi o
Ẹnyin ti ngbọ mi,
T'awọn Baba wa
Fi i ṣaanu ẹda,
Ti nwọn maa nṣe
Aanu alejo.
Nw n a ni
Nitori "abiyawo
Ki i da 'yawo l'oro";
Nwon a ni,
Nitori:
Awọn ko mọ
Iru ọna ajo
T'ọmọ awọn nre.
Bi ẹ ko ba gbagbe o
Gbogbo ẹni pata
T'o ti ngbọ wa:
Idi ọrọ ree
Ti a fi sọrọ
Pe, bi a ba ṣoore
Ti o tọ n'ile aiye,
Bi a ba ṣe 'ranwọ
T'Oluwa mi fẹ f'enia;
B'enia ko mọ ọn
Aala yio mọ ọn, o daju;
O le ran ẹni dudu,
O le ran ẹni funfun,
O le ran ko-funfun ko-dudu
Ti njẹ Mọlato.
Nitorina,
Oore t'o dara ni
Oore t'o tọ;
Oun l'oore atata
T'Ọba Oluwa mi fẹran;
Gbogbo oore ti ko tọ,
Oore aṣedanu ni,
Oore ẹṣẹ,
Oore ti ko l'abọ;
Aya fi ẹni ti
Yio ṣoore ọhun tan
Ti yio tun jiya kun un;
Ẹ tẹti, ẹ gb'ọrọ yi
Ẹnyin ọmọ araiye:
Ẹnikan nwa
Mọto ayọkẹlẹ kọja,
O ri ọkunrin
Ati Obinrin nwọn ndu ro
Lati wọ Danfo,
O ri ọkunrin
Ko ran an lọwọ
O ri abiyamọ
T'o panumọ t'o duro,
O kọ, ko gbe e
O wa bugada
O gbe Obinrin miran,
Ọkọ iyawo ri i,
O d'iṣẹ, o dogun,
O di Ija l'oju ọna.
Ayọkẹlẹ jona,
Apa alayọkẹlẹ da !
Asẹhinwa, asẹhinbọ,
O d'ẹni ti
Ko ni mọto mọ
T'o nf'ẹsẹ tu'gboro!
Oore d'ọran !
Oore di gbese,
Oore d'iya,
Oore d'abamọ,
Oore d'ọṣi ni
Eleyi yio maa jẹ o
Ẹnyin ara wa.

ỌLỌLA ATIORO

# Olagbenro yio da iṣe sile l'Ogbomoso

GBAJUMỌ onisowo kan ni ilu Jos ni Oke-Ọya, Alagba D. O. Ọlagbenro, ti ṣe ileri pe laipẹ yi ni oun yio wa da iṣẹ kan silẹ nilu Ogbomọṣọ ki awọn mẹkunnu ba le ni anfani lati ri iṣẹ ṣe ni ilu na.

Ọgbẹni Ọlagbenro tọkasi eto Iṣẹ Bọọsi ti oun gbekalẹ lati ilu Jos wa si Ogbomọṣọ. O ni Naira mẹwa ni mọto Ijọba ngba l'ori ero kan lati ilu Jos wa si Ogbomọṣọ, ṣugbọn Naira mẹfa pere ni oun ngba, nipa eyi ti o mu ki awọn ọmọ Ogbomọṣọ le maa wa sile nigbagbogbo pẹlu irọrun.

Siwaju si i, Ọgbẹni Ọlagbenro sọ pe, o tọ o si yẹ ki ọmọ Ogbomọṣọ fọwọsowọpọ lati da iṣẹ silẹ ki eto aje ilu na le gbegba oroke, ki awọn ọmọ ilu si le ri ṣe.

Laipẹ yi ni Alagba Ọlagbenro sọrọ na nilu Ogbomọṣọ nibi ayẹyẹ ti Ẹgbẹ ọdọ kan ti njẹ Ogbomọṣọ Youths Association (OYA) ṣe fun un nipa fifi i jẹ Babasalẹ Ẹgbẹ na.

Alagba Ọlagbenro dupẹ lọwọ Ẹgbẹ na fun fifi oun joye na, o si ṣe ileri lati lo ipo na fun ire Ẹgbẹ na ati ti ilu Ogbomọṣọ lapapọ.

Ninu ọrọ Ẹgbẹ na nibi ayẹyẹ na, nwọn sọ pe, Ẹgbẹ ọdọ na wa fun ire ati ilọsiwaju ilu Ogbomọṣọ ati agbegbe rẹ pẹlu iṣọkan ati alaafia ilu na, eyi ni o si mu ki awọn maa lakaka lati maa lepa aniyan na. Nwọn ni awọn lero pe iru Alagba Ọlagbenro yio jẹ ohun elo rere lati mu aniyan awọn na ṣẹ.

Ọpọlọpọ ọmọ ẹgbẹ lati ilu Jos, ile ati ẹhin odi ni o pejupesẹ nibi ayẹyẹ na, bẹẹ ni awọn aṣaaju Ẹgbẹ na sọrọ iwuri nibẹ pẹlu.

Ara awọn enia ti o sọrọ nibẹ na ni Alaga wọn, Ọgbẹni Adebisi Adeniji ẹni ti o kesi gbogbo ọmọ Ogbomọṣọ nile ati lẹhin odi lati maa fi ifẹ ba ara wọn lo ati lati maa gbaruku ti ẹnikẹni ti o ba fẹ gbe ilu na ga.

Ara awọn enia ti o tun sọrọ nibẹ ni Ọgbẹni J. A. Adelẹyẹ lati Jos, Ọmọ Ọba Alao Ọkanlawọn ti iṣe Baba Ẹgbẹ, Iya Ẹgbẹ Iyaafin Bintu Oluwofin.

Ara awọn ọmọ Ẹgbẹ ti o tun wa nibẹ ni: Akande Onitaba, Alagbe Alayan, Ọmọ Ọba Ayọ Oyewumi, Amofin Atilade Ojo, Alhaji Salawu Fọlaranmi, Haji Ramọni, Alufaa Raji Ladipọ, Gboyega Oyediran, Adigun, Haji Sunmọnu, Maria Oyepade, C. Ogundipẹ, Limọta Alajaawa, Ṣẹrifatu Ogundipẹ ati bẹẹbẹẹ lọ.

## Alhaji Okunola jade l'aiye

NWỌN ti kede iku Oniwaasu Musulumi kan nilu Iragbiji, Alhaji Sunmọnu Okunọla ni agbole Ọdọfin nilu Iragbiji ni agbegbe Ọṣun.



ALHAJI S. OKUNỌLA

Nwọn sọ pe o lo to ọgorin ọdun l'aiye gẹgẹ bi nwọn ti wi.

Ọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ ni a gbọ pe o gbẹhin rẹ. Ara wọn ni:- Karimu Atanda; Sabitiyu Aṣande, Sule Ajao ati Ramọni Asunmọ.

Nwọn ti sinku rẹ ni ibamu pẹlu ofin ẹsin Islam, ọpọlọpọ enia ninu ẹni ti ẹlẹgbẹjẹgbẹ Ijoye ati awọn aṣaaju ẹsin jinkojinko wa lo peju sibẹ.

# 4 6 23

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (52)

Lawuyi Ogunniran
ỌỌKU l'oni o Alajao mi
Iji Alugbe, Baba Kafilatu.
Iyawo rẹ nkọ,
Ṣe nbẹ l'alaafia ara ?
Ẹ ẹ ya, ẹ ẹ ra, ẹ ẹ ni i tẹ.
Ṣe o ko gbagbe ọrọ ijọsi
Ti a sọ ti l'ori ẹṣẹ wa
Ti nko ba wa nile,
Ti nko ba wa l'oko,
T'o si nfa iya ba wa ni Naijiria ?
Mo wa fẹ ki o sọ ẹṣẹ yi,
Ki o sọ ọ fun Naijiria
K'onikaluku le ṣọra
Pẹlu iwa wọn gbogbo,
Ki nwọn le jawọ ẹṣẹ dida,
Ki nwọn le ṣe atunhu iwa.
Ẹni a ba wa ki nilọ ọran
T'o ba ṣe bẹẹ ti ko ba gbọ,
Ẹni a ba sọ fun
Pe, ko yee ṣe buburu
T'o kọ ti ko ṣe rere;
Eniyan ti ki nilọ ẹṣẹ,
T'o ṣe bẹẹ ti ko piwada,
A jẹ pe, ibi t'o ba ja si,
Iru wọn l'a a maa polongo
Pe, awọn l'eṣu ọdara
Ti nko ba ni ni Naijiria.
Nitorina ọmọ Ajiṣegiri
Tete maa sọ iru ẹṣẹ
T'ọmọ Naijiria nṣẹ,
T'o nko iya ba wọn n'ilẹ wọn.

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ayinde ! Maa gbọ ọmọ Ejigbọjọ,
Ṣe ki i ṣe pe o muti yo ?
Ṣe o ko mu agadangidi ọti agbagba ?
Ogogoro ni npa ọ ni
Tabi taba eṣubeleke
Ti nwọn npe ni digbolugi ?
Tabi eti rẹ ni ko ṣiṣẹ ?
Tabi o ngbagbe ọrọ ?
Ṣe mo ti sọ fun ọ
Pe, Ẹnu mi kọ ni
Nwọn yio ti gbọ
Pe, oju iya Baalẹ fọ?
Mo ni k'a jawọ ninu ọrọ yi
K'a tara wa omiran sọ.
Tabi o ti gbagbe alaye
Ti mo ṣe l'ẹsẹ t'o gbẹhin ?
Bi o ba gbagbe, ọmọ Ejigbọjẹ,
O ba tete jẹwọ
Ki ng fun o l'oogun isọye.
Boya bi o ba nl'oogun isọye yi
O maa ranti ọrọ ajọsọ wa;
Ma jẹ k'a s'ọrọ l'ori eyi mọ
Jẹ k'a maa ba omiran bọ:

Lawuyi Ogunniran
Ọrọ l'ẹ ngbọ yi o
Gbogbo ẹnyin ti ngbọ wa
A ni k'ọmọ Ajiṣegiri sọ;
Ọmọ Ajiṣegiri taku,
A gbiyanju ko le sọrọ
Ọmọ Ajiṣegiri kọ jalẹjalẹ.
Oun l'o mọ 'di ọrọ,
Oun l'o kọ lati sọ 'di
Ọgbọn ki l'a le da
Ọgbọn ki l'a le ta,
Iwa wo l'a le hu f'ẹni
T'o kọ ti ko sọrọ . . . ?

Adeyẹmọ Ọjẹrinde
Ayinde ! O to 'yara panumọ
Yara danu ọrọ duro
Ki o gbesi ọrọ rẹ t'oo sọ.
Asọnilẹnu pata ni ọmọ Ejigbọjọ
Eniyankeyan ni ọ
Tii sọ ni dọta eniyan
Bawo l'o ṣe fẹ ba mi jẹ
L'oju awọn ti ngbọ wa,
O fẹ sọ mi d'ọta
O fẹ sọ mi di sugọmu.
Ẹnyin onkawe, ẹ jọwọ
Ẹ ma da a lohun ojare
Nṣe l'o ngbiyanju
Lati sọ mi d'ọta Naijiria
Mo wa fẹ ki ẹ teti
Ki ng gba nyin n'imọran:
Mo fẹ ki gbogbo nyin jawọ
Nibi iwa buburu pata;
Ẹ ma huwa ika,
Ẹ ma ṣe 'bi s'ọmọnikeji:
Ẹ ma huwa ẹṣẹ mọ
Ninu iṣe nyin gbogbo,
Ẹ ma si gbẹkẹle Ooṣa
Nitori gbogbo eyi ko tọna,
O nko ba ni ni Naijiria.
Oniruuru iwa ibi gbogbo
L'o kun ọwọ ọmọ araiye:
K'a tori owo
K'a ṣe ibi s'ọmọ araiye;
K'a tori ipo
K'a ṣe eniyan l'ọpọ ika;
K'a tori ẹsun eke,
K'a maa w'ọna ibi f'ọmọ ọlọmọ,
K'a maa ṣeke.
K'a maa ṣe ṣọbẹṣelu,
K'a maa wa ọna aitọ
Lati fi janba ọmọnikeji.
Ọpọ iwa l'o nbẹ nilẹ
T'ọmọ araiye nhu
T'o buru patapata;
Ti ko ṣe e sọ:
K'a maa binu ara ẹni
Bii k'a ku, bii k'a ku;
K'a maa huwa ika
Bi ẹni pe ko ni i si ẹsan
L'ori ohun a ba ṣe gbogbo;
K'a gbimọ ọtẹ l'abẹnu
K'a maa gb'ẹmi eniyan,
K'a maa ṣe ipade eke
Lati huwa ibi s'ẹni elẹni:
K'a maa huwa ika
Bi ẹni pe, a ko ni i d'ero ilẹ;
K'a rakaka m'aiye
Bi ẹni pe a o gbe aiye ju si;
K'a ma le ronuwa
Pe, b'o ti wu k'ẹda lakaka to
B'Ọlọrun ko ba lọwọ si i
K'o ni i le da ohun t'o fẹ da
T'o fi npete iwa ibi.
Gbogbo iwa t'ẹda nhu niyi
Ti nfa 'binu Ọga Ogo;
Ẹ yara sa fun 'ru iwa yi
Nitori Oluwa ko fẹ bẹẹ.
Imọran mi niyi ọ
Gbogbo janmaa wa.
Bi Ayinde ba wa fẹ sọrọ
K'o sọ gbolohun meji.

Lawuyi Ggunniran
Mo ni ohun ti ng o wi
Ọmọ Ajiṣegiri:
Ṣugbọn aaye ko si mọ
Jẹ k'a sọ ọ d'ọsẹ t'o nbọ.


2

6

10

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ,
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10
Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5 Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1)
Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50)
Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi Isin St, Isalẹ Koto P. O Box, 17 Ilọrin.

# Ẹgbọ tẹmi

## Mo fe maa kowe sinu Iwe nyin

OLOOTU,

ỌMỌ ilẹ Naijiria ni mo jẹ. Ṣugbon bayi, ilẹ Austria ni iha Iwo-Oorun ilẹ Oyinbo ni mo ngbe, ti mo ti nṣiṣẹ ajẹ.

O nwu mi ki ng jẹ okan ninu ẹni ti yio maa kowe sinu iwe irohin elede Yoruba rẹ lori ohun ti o jẹmo ẹkọ ati nipa fifi oye ye onkawe nipa igbega aṣa Yoruba.

Ṣugbon inu mi yio dun bi ẹ ba le jẹ ki ng mọ daadaa si i nipa iwe irohin nyin yi: Boya awon enia ilu kan l'o ko ara won jọ ti nwon da a silẹ tabi bi o ṣe pe nipa iru ona miran ni.

Mo tun fẹ mọ iru eto ti ẹ ba nfẹ ninu iwe na ati bẹẹbẹẹ lo.

Mo nfẹ esi ọrọ mi yi kiakia.

Emi ni,

Ọgbẹni B. Aloba,
1030 WIEN,
DIETRICHGASSE
46/6,
AUSTRIA,
W. EUROPE

AKIYESI

Ọrẹ wa Alọba,

A dupẹ lowo rẹ fun ife ti o ni si Imọlẹ Owuro nipa pe, bi o tilẹ jẹ pe iṣẹ po fun o ni okun-eremi ti o wa o nfẹ lati wa aaye lati nipa ninu igbega iwerohin wa ati ti aṣa Yoruba gẹgẹ bi ẹya patapaki kan.

Awon omo orilẹ-ede yi diẹ kan l'o da ile iṣẹ yi sile fun anfaani awon enia wa ti ko kẹko de ibi ti nwon fi le maa ka iwerohin elede Oyinbo ki awon na lẹmo ibi ti aiye nlọ.

Bakanna ni iwe na tun wa fun igbega ede ati aṣa Yoruba. Awon nkan wonyi ni a nlepa, awon na si ni eto ti a gbe igbọwọgbẹsẹ wa gbogbo le lori.

O dabi ẹni pe a ntẹ awon enia l'orun nipa nkan wonyi, a ko si ni i fẹ ki ẹnyin ti ẹ wa ni "Ilu – mọ – jaku" ṣopo lati maa kọ nipa nkan wonni ranṣẹ si wa.

Nitorina, yio dara bi ẹ ba kuku fe maa kọ ifi-nkan we-nkan nipa igbesi aiye awon ara Austria ati Yoruba ṣọwọ si wa ni olorijori ati ni ṣoki, a o si maa tẹ ẹ jade ni oruko nyin pẹlu aworan nyin.

Ṣugbon, a ko ni agbara lati maa sanwo fun ohunkohun ti ẹ ba kọ ranṣẹ ṣugbon a o mọ riri iṣẹ nyin gẹgẹ bi ara awon ti o ko ipa pataki l'ọfẹ fun igbega iwerohin wa, aṣa wa ati ede wa.

— OLOOTU

## Imoran fun Ijoba papo l'ori ijanba moto

OLOOTU,

Ẹ dakun ẹ gba mi l'aye lati ke magba si Ijoba Ologun Orilẹ-ede Naijiria nitoripe ẹni ti o ba ke magba ni a ngba. Ẹbẹ mi siwaju Ijoba wa ni pe:-

Iku moto ti o nko ọgọọrọ awon ọdọ ti ireti, ọjọ ọlọ orilẹ-ede yi wa fun lọ sorun airotẹlẹ lojojumo yi, k'a ṣe nkankan nipa rẹ.

A gbadura titi, o dabi ẹni pe Ọlorun ko gbo, ẹbẹ ni Ọlorun ngbo ṣugbon awon enia ti Bibeli pe ni "alailofin ati alaigboran" ko jẹ ki adura naa gba. I Timoteu 1:9.

Lẹhin aṣaro ojoojumo, ero ti o wa sọkan mi ni pe, ki ng fun Ijoba ni imoran, eyi ti mo si ro pe bi nwon ba tẹle; opin ti yio de fun iku moto ti o gbode kan yi, Adura ti awon enia Ọlorun ngba yio wa ni eso.

(Woju Ewe Kẹfa)

FOR ALL YOUR

Electronics

Fans, Cookers, Radio sets, T.V. Colour T.V. sets, coolers etc: at resonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola Commercial Electrical Store:

N27 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

# Akédé ọ̀nà Ìyè

# A O Re agberaga sile (2)



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

"OHUN mẹfa li Oluwa korira, nitootọ, meje li o ṣe irira fun ọkan rẹ: Oju igberaga, eteeke ati ọwọ ti nta ẹjẹ alaiṣẹ silẹ, Aiya ti nhumọ buburu; ẹsẹ ti o yara ni ire sisa si iwa ika. Ẹlẹri eke ti nsọ eke jade, ati ẹni ti nda ija silẹ laarin awọn arakunrin". Owe 6: 16–19.

Ọsẹ ti o kọja yi ni a bẹrẹ iwaasu lori igberaga. Şugbọn ninu iwaasu t'oni yi, adanu ti igberaga nfa ba enia ni a o sọrọ le. Igberaga ti a wi yi ni o maa nṣe idena ire fun onigberaga enia.

Adanu ti igberaga maa nfa'wa ba enia pọju. Bi onigberaga ba tilẹ nsin Ọlọrun, ko ni i ṣai fi ara rẹ han ninu ẹsin, eyi ti o le mu gbogbo iṣẹ rẹ ninu isin ja si ofo. Bi onigberaga ba si kọ ti ko sin Ọlọrun, bi iru ẹni bẹẹ ti npadanu ire l'ọdọ enia ni yio maa padanu ire l'ọdọ Oluwa.

Bi o ba jẹ ọmọbinrin ni onigberaga na ti ko si ti l'ọkọ; kaka ki o fi ọrọ rẹ sinu adura ki o si fi ọna rẹ le Oluwa lọwọ ki Oluwa le tọ ọ sọna, nṣe ni ọgbọn ara rẹ yio maa jọ ọ l'oju. Ki yio ka Ọrọ Ọlọrun kun nkankan, yio si tẹ ẹ l'ọrun lati maa ba ọmọkunrin ti ki yio fẹ ẹ ni iyawo lọ lati owurọ di alẹ ju ki o gbadura si Ọlọrun Ẹlẹda rẹ lọ.

Bi o si jẹ ọdọmọkunrin ni o ba jẹ onigberaga lati igba ewe rẹ wa, ti o nfi akoko isin nile Ọlọrun muti kiri ti o si nfi igba ewe rẹ ṣe agbere, nṣe ni yio maa ṣe aṣedanu.

Nigba na ni yio di ọmuti paraku, yio si di onirinkurin. Yio wa maa sá fun Oluwa. Ati lọ si ile isin yio di itiju, yio si bẹrẹ si i jiya aiye kiri.

Nigbana ni awọn enia ti o ba ri i ninu ijiya ti igberaga gbe e si yio wa maa juwe ile baba rẹ; nwọn yio maa narẹ; nwọn yio maa na-rẹ; yio si di ka ẹlẹya si i, yio si di oniyẹyẹ enia. Iru awọn eni ti a nwi yi ni o maa ntọka si Ọrọ inu Bibeli şugbọn ti ki i tẹle Ọrọ inu rẹ.

Bayi ni ọpọ enia fi igberaga bere igbe aiye rẹ lati igba ọdọ ti ko si fi iwa na silẹ titi o fi de ipo agba, ti igbesi aiye iru ẹni bẹẹ si dojuru. Iru wọn ni o maa nfi arugbo ara ṣe wahala kiri. Awọn ni Oloyinbo maa nsọ ni tiwọn pe, "A fool at forty is a fool forever" eyi ti o tumọ si pe, enia ti ko ba gbọn titi o fi to ọmọ ogoji ọdun, ko le gbọn mọ.

Bẹẹ gẹgẹ ni o ri pe, enikẹni ti o ba gbe ẹwu igberaga wọ lati kutukutu ọjọ rẹ, ti o nhuwa igberaga ti o nsọrọ igberaga, ti o nrin irin igberaga; ti o nmuti igberaga ti o si fi gbogbo aiye rẹ fun igberaga şişe

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

ati lilepa ohun asan aiye yi; ti iru ẹni bẹẹ ko si fi iwa na silẹ titi o fi kọja ọmọ ogoji ọdun, nigbawo ni iru ẹni bẹẹ yio wa yipada ?

Şugbọn l'ode oni iwọ ọmọ enia; aiye ti yipada si ti atijọ. Ẹnikẹni ti o ba jẹ omugọ titi di ọmọ ogun ọdun l'oni, o ṣe i ṣe ki o di omugọ pari aiye rẹ.

Jesu Kristi ri i pe, iwa ọpọ ọmọ enia ninu aiye jẹ iwa igberaga. Ti o ba waasu titi, A tun pa a ni owe fun awọn enia ki nwọn ba le ṣọra fun iwa igberaga.

Iwa igberaga ti pọ kaakiri nibi gbogbo ninu aiye ati ninu ile isin kaakiri. Awọn onigberaga miran tilẹ fẹrẹ le maa fi owo mọ Alufaa l'oju ninu ile isin. O nṣe aṣehan nitori o nwa iyin ọmọ enia.

Iru iwa yi ni o mu ki Jesu Kristi powe awọn enia meji ti nwọn wọ Tẹmpili lọ i gbadura. Ekinni jẹ Farisi, ekeji si jẹ Agbowo-ode. Şugbọn Agbowo-ode jẹwọ ẹṣẹ rẹ, o si bẹ Ọlọrun lati ṣiju aanu wo oun. Nitoripe Agbowo-ode na jẹwọ ẹṣẹ rẹ, o ri idariji gba l'ọdọ Oluwa.

Şugbọn ekeji ti iṣe Farisi gbadura tirẹ pẹlu igberaga. O nsọ ninu adura rẹ pe oun jẹ ẹni mimọ ati pe oun ko dabi ọkunrin Agbowo-ode, enikeji oun ti i ṣe ẹlẹṣẹ.

Eyi Farisi ti a nwi yi jẹ ẹni ti o maa ndawo nile isin, o si nṣe ohun gbogbo l'orişirişi. Şugbọn ninu gbogbo atunṣe ti o nfi ẹnu ara rẹ ṣe yi, sibe, ẹmi igberaga "Ko s'ẹni t'o dabi mi" nbẹ ninu rẹ, eyi ti o fi ntọkasi Agbowo-ode nni gẹgẹ bi ẹlẹṣẹ.

Şugbọn ọkunrin Farisi na ti ẹmi igberaga kun inu rẹ ko ri idalare gba l'ọdọ Oluwa. Nitorina ni Jesu Kristi ṣe sọ pe: "Ẹnikẹni ti o ba gbe ara rẹ ga, oun l'a o rẹ silẹ. Ẹnikẹni ti o ba si rẹ ara rẹ silẹ oun l'a o gbega" Luku 18; 9-14.

Nje nitorina. iwọ ọmọ enia, Ọrọ Ọlọrun tun nwi fun ọ l'oni pe ọpọ iku ati idaamu ti nbẹ ninu aiye ode oni l'o jẹ pe igberaga l'o nfa a. Maṣe jẹ onigberaga enia nitori pe, a o rẹ agberaga silẹ.

ADURA

Oluwa, ma ṣe jẹ ki igberaga wọnu ọkan mi. Bi o ba si wa ninu ẹjẹ mi, Oluwa, ba mi le e jade, Aamin.


## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.



## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyokan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
(1) N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin



ADIRẸSI OLOOTU

LOOTU,
IMOLE OWURO,
P.M.B. 5230,

# Ijanba moto mu enia marun rorun

ENIA marun ni o ku lẹsẹkẹsẹ ti ọpọlọpọ enia si farapa ninu ijanba mọto kan ti o ṣẹlẹ lori afara Idẹmili l'ọna Onitṣa silu Oweri ni aipẹ yi.

Irohin sọ pe mọto na forigbari pẹlu mọto "ajugbe-ejo" lori afara Idẹmili l'o fa ijanba na. Enia mẹta l'o ku lẹsẹkẹsẹ nigba ti ijanba na ṣelẹ, meji si ku nigba ti awọn ngbe wọn lọ sile iwosan.

A gbọ pe, onisowo ni awọn ero ọkọ na, awọn Ọlọpa si ti gbe oku awọn enia marun na lọ sile iwosan ilu Onitsha fun ayẹwo, ati awọn ti o farapa fun itọju.

# Igi wo pa gende

IROHIN lati ilu Ọfa ni Ipinlẹ Kwara fi ye wa pe, igi ti wo pa ọkunrin agegi kan sinu oko ni ilu na.

Laipẹ yi ni iṣẹle na ṣẹlẹ gẹgẹ bi a ti gbọ. Irohin sọ pe ọkunrin agegi na gbajumọ pupọ nibi iṣẹ igi-gige, ki o to di pe igi ti o nge wo pa a ni ọjọ ti a nwi yi.

Irohin sọ pe, bi ọkunrin ti a wi yi ti nge igi rabatarabata kan ninu igbo ni ẹba ilu na, ni igi na yẹwẹrẹ, ti o si wo lu u mọlẹ.

A gbọ pe awọn alaanu sare gbe e lọ sile iwosan ilu Ọfa fun itọju ṣugbọn ẹpa ko ba oro mọ.

# Ademola f'abo fun Jemibewon

NI aipẹ yi ni Alaga Igbimọ ti nṣe iwadi l'ori ilana Ọba jijẹ si awọn itẹ Ọba bii melo kan ni Ipinlẹ Ọyọ, Ọlọla Adenẹkan Ademọla, fi abọ iṣi-keji iwadi ti o ṣe le Gomina Ipinlẹ Ọyọ, Ọgagun David Jẹmibẹwọn lọwọ.

Nigba ti o ngba iwe abajade Igbimọ na l'orukọ Ijọba, Ọgagun Jẹmibẹwọn dupẹ lọwọ Igbimọ na fun iṣẹ ribiribi ti nwọn ṣe, o si kan saara si wọn pẹlu

A o ranti pe Ijọba Ipinlẹ na l'o gbe Igbimọ Iwadi na jade lati wadi awọn ilana Ọba jijẹ kan ni Ipinlẹ Ọyọ ki Ijọba ba le ṣe atunṣe ti o ba yẹ l'ori rẹ.

**NIGERIA NEW STATES CO.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.

**Nap 3 4 5**

# Imoran fun ijoba l'ori ijanba moto

(La ti Oju Ewe Kẹrin)

Awọn imoran mi na niyi:

Ekini - Ki ijoba da awon olopa inu sita ki nwon maa wo onirũru Moto ki won le maa mu awon arufin awako.

Ekeji:- Awako ti o ba sare koja osunwon ti Ijoba fun iru ọkọ bẹẹ, ki nwon gba iwe aṣẹ ti ijoba fun un.

Ẹkẹta:- Mọto ti ko ba ni ami ti yio fi odiwon ere ti o nsa han ni ki nwon gba iwe ẹri ti o fi wako.

Ẹkẹrin:- Awako ti o ba nya elegbe rẹ silẹ nibi ti o lodi si ofin ni ki nwon gba iwe aṣẹ ti o fi nwako lowo rẹ.

Ẹkarun:- Awako ti o ba gboko kalẹ ni irona, ti o ya si ile ọti ni ki nwon gba iwe aṣẹ ti o fi nwako lowo rẹ.

Ẹkẹfa:- Ki ijoba si maa fi ofin de iru iwe irinna bẹẹ fun odun mẹta.

Ekeje:- Ki ijoba si maa fi aworan iru awon alaigboran bee sinu iwe irohin ki gbo gbo enia le mo won gẹgẹ bi arufin, ki gbogbo enia le ni agbara lati mu iru awon enia bẹẹ.

Bi Ijoba ba le gba oro mi yi yẹwo, ogun ekun ki-koro ti o gba orilẹ ede wa kan yi yio dopin.

Emi ni Pastor J. O. Amọo,
C. A. C.
P. O. BOX 59,
Ilaro—Ogun State.

**1**

**2**



ỌGBẸNI OLUFẸMI ṢODẸINDE
Alakoso ṢODẸINDẸ BROS. (Nig) LTD.

# Ejo Sodeinde ati Banki ntesiwaju

NINU ẹjọ onirinwo ọkẹ Naira (₦8million) ti Alakoso Ilẹ Iṣẹ SHODEINDE BROTHERS (NIG) LIMITED, Ọgbẹni Olufẹmi Ṣodẹinde pe ile ifowopomosi African Continental Bank Limited (ACB), enia meji ọtọtọ ni o jẹri nile ẹjọ.

Ọgbẹni Ṣodẹinde l'o pe Banki na l'ẹjọ pe o ṣe tanadi fun oun l'ori iṣẹ nla kan ti oun fẹ dasilẹ nilu Iganna ni iha Ariwa ilẹ Ọyọ nipa pe Banki na kọwe ibalorukojẹ nipa Ile Iṣẹ oun ti o fẹ da iṣẹ na silẹ.

Nitori ọran yi ni Ọgbẹni Ṣodẹinde ṣe pe Banki na lẹjọ pe ki ile ẹjọ giga na ba oun gba

(Woju Ewe Keje)




# Ajisaari di Alare Sakara

**Lati Owo Bolaji Babalola**



ỌGBẸNI AJADI BALOGUN
Ajisaari t'o di Onisakara

GBAJUMỌ alare ajisaari kan nilu Eko tẹlẹ, Ọgbẹni Ajadi Balogun, ti fi are ajisaari silẹ, o si ti nba are sakara lọ ni sẹpẹ.

Ajadi Balogun ko kẹrẹ rara nibi are ajisaari ki o to bọpabọsẹ kuro ninu iru are bẹẹ.

Igba mẹta ọtọtọ ni o gba ife ẹyẹ idije are ajisaari nilu Eko. Ninu ọdun 1969, o gba eyi ti o waiye ni adugbo Oluwọle labẹ Alaga Alhaji F. A. Maṣa.

Ninu ọdun 1970 ni o gba ife ẹyẹ bakanna, eyi ti Ẹgbẹ Muslim Ramblers ṣeto rẹ ni gbangba Ọnala ni adugbo Isalẹgangan nilu Eko.

Ti ọdun 1971 ti o tun gba waiye l'abẹ Alaga Alhaji Faṣina ti iṣe Ọga kan pataki ninu iṣẹ Ijọba Eko nigbana.

Ṣugbọn ninu ọdun 1972 ni o fi are ajisaari silẹ. Ohun ti Ajadi Balogun sọ pe o fa a ni pe, awọn ẹgbẹ ajisaari kan njowu oun, nwọn si sọ pe ti oun ba fi le wa sibi idije ti ọdun 1972 na ti yio waiye ni City Hall Eko, pipa ni awọn yio pa oun.

O ni eyi ni o mu ki oun fi are ajisaari silẹ ti o si kọjumọ iṣẹ Porter ti o nṣe ni Yunifasiti Eko.

Ajadi Balogun sọ fun mi pe, nigba ti awọn olufẹ are oun bẹrẹ si i yọ oun l'ẹnu lati maa ṣere ni oun ba kuku da Ẹgbẹ Alare Sakara silẹ niwọn ọdun merin sẹhin; ati pe ẹgbẹ alare na ti di araba bayi.

Nwọn bẹrẹ si i pe Ajadi Balogun ati Ẹgbẹ Alare sakara rẹ kaakiri ilu nlanla ni ilẹ Yoruba bi: Eko, Ibadan, Ijẹbu-Ode ati awọn ilu bi Amuwo, Iganmu-Orile, Ikẹnẹ, Ikorodu ati bẹẹbẹẹ lọ.

Bakanna ni ile ijo olokiki kan ni Surulere ti njẹ New Surulere Club ti gba a lati maa ṣere ibilẹ fun awọn onibara rẹ nibẹ, a si gbọ pe nṣe ni ero maa nkun ni akunya ni ọjọ ti Ajadi Balogun ba fẹ ṣere.

AWO RẸKỌỌDU

Ni ipari ọdun ti o lọ yi ni awo rẹ akọkọ ti o ṣe si ọdọ AIYELỌJA RECORDS jade Nọnba awo na ni SSAL 481, eyi ti mo gbọ pe o ta daradara.

i

Awo ti akọkọ y. tubọ mu ki okiki Ajadi Balogun kan si i ati pe, eyi ni o ta a nidi ti o fi ṣeto awo keji, eyi ti mo gbọ pe yio jade laipẹ yi. Mo gbọ pẹlu pe awo na yio fakiki.

AWỌN ALARE

Ohun elo ti o dara ni ẹgbẹ alare na nlo, awọn enia mejila ni o si wa ninu Ẹgbẹ na. Ajadi Balogun ti iṣe ọgwọn ni o nta doje at moolo, Adetọṣọ Balogun ni o nlu iyaalu, Ọlayiwọla Arẹmu ni ọlọmọle, Kọlawọle Ṣokunbi ni o nta igba, Tajudeen Amuda ni nlu ogido, Mufutau Anthony nlu onibeji. Awọn elegbe ni: Fatayi Ogunkọya, Amuda Balogun, Karimu Raji ati Suraju Tijani.

# Ejo Sodeinde

(Lati Oju Ewe Kẹfa) rinwo Naira lọwọ Banki na gẹgẹ bi owo itanran orukọ ile iṣẹ oun ti nwọn bajẹ ati tanadi ti wọn ṣe fun oun l'ori Iṣẹ nla ti oun fẹ dasilẹ.

Ninu ẹri rẹ ni ọsẹ ti o kọja nile ẹjọ giga kan ti nṣẹjọ na nilu Ibadan, gbajumọ wọnlẹwọnlẹ kan, Oloye Samuel Ogunbiyi, sọ fun ile ẹjọ na pe ninu ọdun 1972 ni ile iṣẹ ṢODẸINDE BROTHERS gbe iṣẹ ilẹ wiwọn kan fun oun ni Iganna ni igberiko ilu Ọyọ. O ni ilẹ na jẹ ọkẹ meji abọ sare ilẹ (50,000 acres); iye owo iṣẹ ti oun si pinnu lati gba lowo ile iṣẹ na gẹgẹ bi owo iṣẹ ilẹ wiwon na jẹ okẹ meje-abọ Naira (₦150,000.00).

Oloye Ogunbiyi ṣipaya pe, ẹẹdẹgbaata Naira (₦5,000.00) ni ile iṣẹ Ṣodẹinde Brothers kọ san ti iṣẹ na fi bẹrẹ,

Siwaju si i, Oloye Ogunbiyi sọ fun ile ẹjọ na pe, Naira mẹta l'ori sare ilẹ kan ni awon dunadura owo wiwon ilẹ na si pẹlu ile iṣẹ Ṣodeinde Brothers, ṣugbon pe, ile iṣẹ na ni o nilati ṣan aala ilẹ na.

Oloye Ogunbiyi fi kun un pe awọn onimo ti o daju ti oun ko lo sibi iṣẹ na po, bẹẹ ni ile iṣẹ na si nsanwo iṣẹ na deede titi di nkan bi idaji odun 1974 ti ile iṣẹ na ko sanwo fun oun mo.

Oloye Ogunbiyi so pe nigba yi ni oun wa jẹ ki ile iṣẹ na mo pe oun yio pe won l'ẹjo gbese. O ni ṣugbon nigbati Ọgbẹni Olufẹmi Ṣodẹinde ba oun soro ni ko jẹ ki oun pe ile iṣẹ na l'ẹjo nigbana, ṣugbon nigba ti o di odun 1975 ni oun pe won l'ẹjo nigba ti oun ko le faramo on mo.

Siwaju si i, Oloye Ogunbiyi sọ pe ninu oṣu kinni ọdun 1975 ni oun pẹjọ na, ile ẹjọ si fi ọjọ ẹjọ gbigbọ sinu oṣu karun ọdun na. O ni Ọgbẹni Ṣodẹinde tabi Agbẹjọro rẹ ko si wa sile ẹjọ titi ile ẹjọ na fi da oun l'are.

Ninu idahun rẹ si ibeere Agbẹjọro Banki ACB, Oloye Ogunbiyi sọ fun ile ẹjọ na pe, oun ko fi girimakai mu idajọ na ṣẹ le Ọgbẹni Ṣodẹinde l'ori nitoripe aanu rẹ nṣe oun nitoripe Ọgbẹni Ṣodẹinde ni awọn ẹjọ miran l'ọrun ti o njẹ ni akoko na.

Nigbati Agbẹjọro na beere bọya inu rẹ dun lati wa jẹri gbe onigbese rẹ nile ẹjọ, Oloye Ogunbiyi sọ pe ki i ṣe pe oun finnufindọ wa sile ẹjọ na bikose pe nṣe ni ile ẹjọ fi iwe pe oun.

ẸLẸRI MIRAN

Ẹlẹri miran ti o tun jẹri nile ẹjọ na ni Ọgbẹni L. O. Fawọle, ẹni ti o sọ pe, oun ni oun ṣiṣẹ l'ori bi a ti ṣe le maa ṣe ibominrin ni ori ilẹ kan ni Iganna fun ile iṣẹ Ṣodẹinde Brothers (Nigeria) Limited.

O ni oun ni o ṣiṣẹ bawo ni eto ibominrin na ṣe le waiye lẹhin ti ibi iṣẹ imo ijinlẹ nipa ohun ogbin ti kesi oun lati ṣe bẹẹ.

Ọgbẹni Fawole so pe ibi iṣẹ ti Yunifasiti na l'o pese ohun elo ti oun lo l'ori ilẹ na, oun si fi abọ iwadi oun le ibi iṣẹ na lowo ni Yunifasiti ibadan.

Siwaju si i, Ọgbẹni Fawole so pe, ile iṣẹ Ṣodẹinde Brothers l'o pese ile gbigbe, ounjẹ, ina, omi ati ohun amuludun miran fun oun ni akoko iṣẹ na.

Nigba ti o ndahun ibeere kan lati odo Agbẹjoro Banki na, Ọgbẹni Fawole so pe oun ti ṣe iru iṣẹ bẹẹ fun Ijoba Apapo Naijiria ninu odun 1972 ati 1973.

Agbẹjoro ile iṣẹ Ṣodẹinde Brothers, Ọgbẹni Afẹ Babalola ati Agbẹjọro miran, Ọgbẹni Obe ti awon mejeeji nṣẹnu fun ile iṣẹ na, ni o npapo to ẹlẹri wonyi sona nile ẹjo na. Ẹjo na nlo lowo.

# 'Abileko lu Arugbo pa'

(Lati Oju Ewe Kinni)

ati pe, o finnufindọ fẹ pa oloogbe na l'ara nipa iwa rẹ na ni, ni o fi lu u ni ikuuku ni igba-aiya.

Nitorina, Agbẹjọro na rọ ile ẹjọ lati da obinrin na lẹbi ọran na.

Ṣugbọn ninu awijare ti Agbẹjọro Ẹbun Jacob ṣe, Agbẹjọro na, Ọgbẹni S. B. Ọlanipẹkun sọ pe, ẹsun ti awọn afẹsun—kanni ka si ẹlẹjọ oun l'orun ko le ṣai kuna nitoripe ko fi idi mulẹ.

Agbẹjọro na sọ pe, awọn afẹsunkanni ti kuna lati fi idi rẹ mulẹ pe, iwa ti ẹlẹjọ oun hu ni o fa iku iya arugbo na.

Agbẹjọro na so pe, dandan ni fun awon afẹsunkanni lati fi idi ẹsun won mulẹ gbọningbonin, eyi ti Agbẹjoro na so pe nwon ti kuna lati ṣe l'ori ẹsun na.

Siwaju si i, Agbẹjoro na so pe, awon afẹsunkanni ti kuna lati fi ye ile ẹjọ yekeyeke pe, iwa ti ẹlẹjo oun hu le ju; bẹẹ ni nwon si ti kuna lati fi ye ile ẹjo pe ẹlẹjo oun ni buburu kan lokan lati ṣe si oloogbe na ni.

Nitorina, Agbẹjoro na ro ile ẹjo lati gba ẹri ẹlẹjo oun gbo pe, oun ko lu oloogbe na ni igba-aiya tabi ni ibikibi ni ara rẹ ki ile ẹjo gba pe oro ẹnu awon afẹsunkanni ko mo iyan l'ori ki ile ẹjo si da ẹlẹjo oun silẹ ni alaafia.

Nigbana ni Adajo ile ẹjo giga na, Ọlola Emmanuel Adeyẹmo Adewuyi kede pe ni ojo karun oṣu karun odun yi ni yio ṣe idajo l'ori bi lilu ti nwon lu iya arugbo na ni o fa iku rẹ tabi boya aisan ni o pa a.

# Ina pa omo iya meji

(Lati Oju Ewe Kinni)

aṣọ na sori waya ti nwọn maa nsaṣọ si nibẹ, ni ina ba gbe e, ti o la a molẹ lakọlakọ ti o si paa. Nwọn ni nibi ti ẹgbọn rẹ, *Jimọ* ti ri eyi ti o si ti sare si i lati gba a silẹ ni ina ba gbe oun na ti o si pa awọn mejeeji ju silẹ ni apafọn.

Irohin sọ pe, nigba ti ọrọ ri bayi awon ara ile takete sẹhin, nwọn ko le sun tọ oku na mọ; awon panapana ni o si wa gbe oku mejeeji lọ sile iwosan Ijọba nilu Ado-Ekiti fun ayẹwo.

Iyawo meji ni a gbọ pe eyi aburo fi s'aiye lo, ẹgbon si fi mẹta s'aiye. A gbo pe opolopo omo l'o gbẹhin won pẹlu.

Ẹnikẹni ko le fi owo soiya pe, nkan bayi—bayi l'o fa sababi na ṣugbon irohin kan ti o sunmo ile iṣẹ awon panapana so pe, ojo alafẹfẹ ti o ro ni o gbe waya awon onina kolu waya isaṣo na, ati pe, eyi gan-an ni o nilati fa ijanba na.

Ṣugbon, awon Ọlopa ilu Ado-Ekiti ti bẹrẹ iwadi l'ori iṣẹlẹ na gẹgẹ bi a ti gbo.

# Oyetunde di Ọkere Ago Okere

NI ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu kẹrin ọdun yi ni Ọgbẹni Ṣitu Oni Oyetunde di Okẹrẹ Agọ-Okẹrẹ Igboho ni agbegbe Igbimọ Ijọba Ibilẹ Irẹpọ.

Ọkẹre titun na, Oloye Ṣitu Oni Oyetunde ni Ọkẹrẹ ketala, oun ni o si rọpo Ọkẹrẹ ana, Oloye Aṣiru Oyeṣade.

Musulumi ni Ọkẹrẹ titun na, iṣẹ agbẹ ni o si nṣe ki o to gori itẹ wọn baba rẹ.

10 12 23 48

# IDUPE

NI orukọ gbogbo idile Adewale, mo nfi asiko yi dupẹ lọwọ gbogbo awọn enia ti wọn wa ba wa ṣẹyẹ nigba ti a sin ọmọ wa Morohunmubọ Adefunkẹ Adewale fun ọkọ ni ọjọ kẹsan oṣu yi (9/4/77) ni ile ijọsin First Baptist Church, Idikan, Ibadan.

Adupẹ lọwọ Alufaa Ijọ na, Ọmọwe J. A. Adedokun, Alufaa ijọ Baptist ni Oritamẹfa, Ọmọwe S. T. Ọla Akande ati awon Diakoni ti nwọn lọwọ ninu isin iyawo na. Bakanna ni a dupẹ lọwọ Atẹduru ati gbogbo ọmọ ijọ ti o ba wa nipa ninu aṣẹyẹ na.

A dupẹ lọwọ gbogbo ọrẹ ẹbi ati awọn ẹgbẹ ọmọ Fiditi ni Ibadan ati ẹgbẹ Oke Padre ti wọn ṣe aṣeyẹ na.

A dupẹ lọwọ awọn ọga ile iṣẹ Imọlẹ Owurọ, Oṣiṣẹ School of Nursing, Ẹlẹiyẹle, Chief J. O. Taiwo Chief Ọlagbami, Ọgbẹni J. O. Adeyẹmọ, Alagba V. B. Atilọla, Ọgbẹni S. Oye Bamgbose ati ọpọlọpọ ojulumọ ti gbogbo wọn fun wa ni ẹbun fun ti isinmọfọkọ na.

A dupẹ, Ọlọrun yio fi adun kari, ire bayi ni a o maa ba ara wa ṣe o. Adupẹ o.

Moni Adewale
(Fun Gbogbo Ẹbi)

# ITUFO

TẸDUNTẸDUN ni a fi kede iku iya wa ọwọn: Madam Abigael Wuraọla Lade, ẹni ti o fi aiye yi silẹ ni 19/4/77 lẹhin ti o ti lo ọdun marundinlọgọrin l'aiye.

Nigba aiye rẹ, opo kan pataki ni o jẹ ninu Ijọ St. Paul's Church, Ajia Ibadan.

Ọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'o gbẹhin rẹ. Ara wọn ni Ọgbẹni J. Oyebamiji Lade ti nṣiṣẹ ni M. A. N. R, Ibadan, Alhaji Oye Oyelade ti o nṣiṣẹ ni ile iṣẹ Imọlẹ Owurọ, Ṣajẹnti Pọju Oyelade, N. A; Abẹokuta.



MADAM ABIGAEL WURAỌLA LADE.

Aisun gẹgẹ bi ilana ti Onigbagbọ yio waiye ninu ile rẹ, E1/280 Bẹiyẹrunka, Ibadan ni ojo Friday 13:5:77, bẹrẹ lati agogo mẹjo alẹ.

Ni agogo mẹrin irolẹ ojo Satide, 14/5/77 ni isin ikẹhin yio waiye fun Oloogbe na ni ile Ijosin Christ Church, Mapo lẹhin eyi ti a o lo sinku ni itẹku Ijo na ti o wa ni Odinjo nilu Ibadan.

Lẹsẹkẹsẹ ni inawo-oku yio bẹrẹ. Ni ojo Sunday ti iṣe 15/5/77 ni isin ijade oku yio waiye ninu ile Ijọsin Ijọ kanna, Christ Church, Mapo

Printed and published by the People's Star Press Limited, H4/466B Yemetu Aladorin P. M. B. 5256, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran. E4/985, Areme Adekile Ibadan. Lagos Office: 16, Odunlami St. Phone 27917.